HOLY CROSS HEALTH
A Member of Trinity Health

# ÀKÍYÈSÍ ÀWỌN ÌṢE ÌKỌ̀KỌ̀

Ọjọ́ tó bẹ̀rẹ̀ Iṣẹ́: 14 Oṣù Kẹrin, Ọdún 2003
Ti Ṣàtúnwò: 1 Oṣù Kẹfà, Ọdún 2024

ÀKÍYÈSÍ YÌÍ ṢÀPÈJÚWÉ BÍ A ṢE LÈ LO ÀLÀYÉ ÌLERA NÍPA RẸ ÀTI BÍ A ṢE LÈ ṢÀFIHÀN RẸ PẸ̀LÚ BÍ O ṢE LÈ RÍ ÌSỌFÚNNI YÌÍ. JỌ̀WỌ́ ṢÀTÚNWÒ RẸ DÁRADÁRA.

A ní láti ṣe bẹ́ẹ̀ ní ìbámu pẹ̀lú òfin ètò ìbánigbófò ìlera, (Health Insurance Portability and Accountability Act) ti ọdún 1996,pẹ̀lú Ìmọ̀-ẹ̀rọ ti Ìsọ̀fúnni Ìlera fún Òfin ti Ìlera Ilé-ìwòsàn àti ti Ọrọ̀ Ajé (Health Information Technology for Economic and Clinical Health Act (ti o wa ni Abala XIII ti Ofin Òfin Ìgbàpadà àti Ìdóko-òwò padà ti Amẹrika (American Recovery and Reinvestment Act) ti ọdún 2009) (ti a tọka si ni apapọ bi "HIPAA"), gẹ́gẹ́ bí a ti ń ṣe àtúnṣe rẹ̀ láti ìgbà dé ìgbà, láti pa àṣírí ìsọfúnni nípa ìlera aláìsàn tí a lè dá mọ̀ ní ìdánimọ̀ ẹni ní ìdánimọ̀ mọ́ (ìsọfúnni yìí ni "ìsọfúnni nípa ìlera tí a dáàbò bò" (protected health information)  tí a sì tọ́ka sí níhìn-ín gẹ́gẹ́ bí "(protected health information) PHI"). A tún ní láti fún àwọn aláìsàn ní Ìkìlọ̀ Ìlànà Ìpamọ́ nípa PHI. A ó máa lo tàbí sọ PHI rẹ di mímọ̀ bí òfin ìpínlẹ̀ àti ti ìjọba àpapọ̀ bá ṣe fàyè gbà á tàbí bó ṣe pọn dandan. Ìkìlọ̀ yìí kan PHI rẹ lábẹ́ àkóso wa títí kan àwọn àkọsílẹ̀ ìṣègùn tí a ṣe.

A mọ̀ wípé ìsọfúnni ìlera rẹ jẹ́ ohun ti ara ẹni gan-an, àtipé a pinnu láti dáàbòbò ìkọ̀kọ̀ rẹ. Jọ̀wọ́ ka Àkíyèsí Àwọn Ìṣe Ìkọ̀kọ̀ yìí fínnífínní. O ń ṣàpèjúwé bí aó ti lò àti ṣàfihàn PHI rẹ.

Àkíyèsí yìí níṣe pẹ̀lú ìpèsè ìtọ́jú ìlera nípasẹ̀ ìlé ìwòsàn wa àti àwọn òṣìṣẹ́ ìlera tí ó wà ní ilé ìwòsàn ńlá, àwọn ẹ̀ka tí ó ń tọ́jú aláìsàn tí wọn kò sùn ilé ìwòsàn àti àwọn ilé ìtọ́jú. Àkíyèsí yìí tún níṣe pẹ̀lú àwọn ìṣàyẹ̀wò ìṣàmúlò àti àwọn ìgbòkègbodò àyẹ̀wò ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ dídára Trinity Health àti ilé iwòsàn wa gẹ́gẹ́ bí ọmọ ẹgbẹ́ Trinity Health, tí ó jẹ́ ẹ̀ka ètò ìlera kátólíìkì kan tí ó ní àwọn ilé ìtọ́jú tí wọ́n wà ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìpínlẹ̀ káàkiri Orílẹ̀-èdè Àmẹ́ríkà.

## I. Lílò tí a yọ̀nda tàbí Ìṣàfihàn.

**A. <u>Ìtọ́jú:</u>** Ẹ̀ka Ìjọba wa yóò lò àti ṣàfihàn PHI rẹ láti pèsè, ṣatukọ̀, àti ṣàkóso ìtọ́jú ìlera àti àwọn ìpèsè tí ó níṣe láti ṣé àwọn ojúṣe ìtọ́jú. Ìwọ̀nyí ni àwọn àpẹẹrẹ bí aó ṣe lò àti/tàbí ṣàfihàn PHI:

i. Sí oníṣègùn tí ó ń tọ́jú rẹ, (àwọn) oníṣegùn tí a ké sí, àti àwọn olùpèsè ìtọ́jú ìlera tí wọ́n nílò irúfẹ́ ìsọfúnni tí ó tọ́ lábẹ́ àmójútó àti ìtọ́jú rẹ.

ii. Láti ṣatukọ̀ ìtọ́jú rẹ (fún àpẹẹrẹ ìṣètò ípinnu fún ìpàdé) pẹ̀lú wa àti àwọn olùpèsè ìtọ́jú ìlera mìíràn gẹ́gẹ́ bí orúkọ, àdírẹ́sì, ìgbanisíṣẹ́, iléṣẹ́ ìbánigbófò, àti bẹ́ẹ̀bẹ́ẹ̀ lọ.

iii. láti kàn sí ẹ gẹ́gẹ́ bí ìránnilétí pé o ní ìpàdé fún ìtọ́jú tàbí àmojútó ètò ìṣègùn ní àwọn ilé ìtọ́jú wa.

iv. Láti pèsè ìsọfúnni nípa àwọn ọ̀nà ìtọ́jú mìíràn, tàbi àwọn ànfààní tàbí àwọn ìpèsè mìíràn tí ó jẹ mọ́ ìlera fún ọ.

v. Tí o bá jẹ́ ẹ̀lẹ́wọ̀n tàbí tí o wà lábẹ́ àtìmọ́ òṣìṣẹ́ agbófinró kan, aó ṣàfihàn PHI rẹ sí ọgbà ẹ̀wọ̀n tàbí òṣìṣẹ́ agbófinró.

**B. <u>Ìsanwó:</u>** Ẹ̀ka Ìjọba wa yóò lò àti ṣàfihàn PHI nípa rẹ láti lè sanwó. Ìwọ̀nyí ni àwọn àpẹẹrẹ bí aó ṣe lò àti/tàbí ṣàfihàn PHI:rẹ

i. Sí iléeṣẹ́ ìbánigbófò kan, olùsanwó ikọ̀ kẹta, alákóso ikọ̀ kẹta, ètò ìlera tàbí olùpèsè ìmójútó ìlera mìíràn (tàbí àwọn aṣojú wọ́n tí wọ́n ní ìgbàṣẹ bó ti yẹ) láti lè san àwọn owó gẹ́gẹ́ bí mímọ agbègbè, yíyẹ ní yíyàn, ìgbàṣẹ / ìyọ̀da ṣáájú fún ìtọ́jú, ìdíyelé, ìṣàkóso àwọn ìsanwó, àwọn ìṣàyẹ̀wò ìdáwópadà, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

ii. Sí àwọn iléeṣẹ́ tó ń gba owó àti àwọn ikọ̀ kẹta tí wọ́n kópa nínú gbígbà owó fún ìtọ́jú.

**C. <u>Àwọn Iṣẹ́ Ìtọ́jú Ìlera:</u>** Ẹ̀ka Ìjọba wa yóò lò àti ṣàfihàn PHI rẹ fún àwọn ìdí àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú ìlera Ìwọ̀nyí ni àwọn àpẹẹrẹ bí aó ṣe lò àti/tàbí ṣàfihàn PHI:

i. Fún ìṣàkóso ẹjọ́, iìdánilójú dídára, ìṣàmúlò, ìṣirò, ìṣàyẹ̀wò, ìṣètò ìdánisílẹ̀, àwọn ìgbòkègbodò ìlera tó jẹ mọ́ ìmúdára ìlera tàbí ṣíṣe àdínkù àwọn owó ìtọ́jú ìlera, ẹ̀kọ́, Ìfọwọ́sí, fífúnni láṣẹ, àti àwọn ìgbòkègbodò ìwé ẹ̀rí.

ii. Sí àwọn olùgbanilámọ̀ràn, àwọn oníṣẹ́ ìṣirò, àwọn oníṣẹ́ àyẹ̀wò, àwọn agbẹjọ́rò, àwọn iléeṣẹ́ aládàkọ, àwọn olùpèsè ìmọ̀-ẹ̀rọ àti ẹ̀rọ ìpamọ́ ayérayé, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

**D. <u>Àwọn èlò àti Ìṣàfihàn mìíràn:</u>** Gẹ́gẹ́ bí ara àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú, ìsanwó, àti ìmójútó ìlera Ẹ̀ka Ìjọba wa lè tún lò PHI fún àwọn ìdí wọ̀nyìí:

i. Àwọn Ìgbòkègbodò Ìkówójọ̀ àti Ìpolówó ọjà: aó lò bẹ́ẹ̀ ni a sì lè ṣàfihàn díẹ̀ nínú PHI rẹ, pẹ̀lú àjọ tí ó bá níìṣe, fún àwọn pàtó ìgbòkègbodò ìkówójọ àti ìpolówó ọjà. Fún àpẹẹrẹ, a lè lò tàbí ṣàfihàn ìsọfúnni agbègbè rẹ, àwọn ọjọ́ tí a pèsè ìtọ́jú fún ọ, ìsọfúnní oníṣègùn tí ó ń tọ́jú rẹ, ẹ̀ka ti olùpèsè àti ìsọfúnni àbájádé bẹ́ẹ̀ ni a sì lè béèrè fún ìdásí ti owó lọ́wọ́ rẹ. Èyí yòówù ìbáraẹnisọ̀rọ̀ tí ìkówójọ tí a bá fi rànṣẹ́ sí ọ yóò jẹ́ kí o mọ̀ bí o ṣe lè lò ẹ̀tọ́ rẹ láti <u>jáde</u> kúrò ní àwọn ìbáraẹnisọ̀rọ̀ tó jọ bẹ́ẹ̀ lọ́jọ́ iwájú.

ii. Ìwádìí Ìṣègùn A ó lò àti ṣàfihàn PHI rẹ lọ́nà tí a yọ̀nda fún àwọn olùwádìí ìṣègùn òyìnbó tí ó bá béèrè fún un fún àwọn iṣẹ́ ìwádìí ìṣègùn tí a fọwọ́sí. Àwọn olùṣèwádìí ní láti dáàbò bo gbogbo PHI tí wọ́n bá rí gbà.

iii. Ìsọfúnni àti Ìgbésẹ̀ Ìgbéga Ìlera A ó lo a ó sì sọ díẹ̀ lára PHI rẹ fún àwọn ìgbésẹ̀ ìgbéga ìlera kan. Fún àpẹẹrẹ, a ó lo orúkọ àti àdírẹ́sì rẹ láti ṣe ìfiránṣẹ́ àtẹ̀jíṣẹ́ ìròyìn gbogbogbò tàbí ìṣọfúnni kan pàtó sí ọ dá lórí àwọn ìfiyèsí ìlera rẹ.

**E. <u>Àwọn òfin Ìjọba Ìpínlẹ̀ àti Ìjọba Àpapọ̀ tó le koko sí i:</u>** Òfin Ìjọba Ìpínlẹ̀ ti [Insert your State] le koko ju HIPAA lọ ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn agbègbè. Àwọn òfin ìjọba àpapọ̀ kan ní pàtó náà le koko ju HIPAA lọ. Ẹ̀ka Ìjọba wa yóò tẹ̀síwájú láti máa tẹ̀lé àwọn òfin ti ìjọba ìpínlẹ̀ àti ti ìjọba àpapọ̀ tó le koko wọ̀nyìí.

i. **<u>Àwọn Òfin Ìjọba Àpapọ̀ tó le koko sí i:</u>** Àwọn òfin ìjọba àpapọ̀ náà ní àfikún àwọn òfin ìkọ̀kọ̀ ẹ̀rọ ayélujára, gẹ́gẹ́ bi Òfin ìdáàbòbò ìkọ̀kọ̀ àwọn ọmọdé lórí àyélujára (Children’s Online Privacy Protection Act) àti àwọn òfin ìjọba àpapọ̀ tí ó ń darí wíwà ní ìpamọ́ ìsọfúnni ìlera nípa ìtọ́jú mímú ọtí àmupara àti lílò òògùn olóró lọ́nà àìtọ́.

ii. **<u>Àwọn Òfin Ìjọba Ìpínlẹ̀ tó le koko sí i:</u>** Òfin Ìjọba Ìpínlẹ̀ jẹ́ ohun tó le koko tí ẹni náà bá lẹ́tọ̀ọ́ láti gba àwọn àgbàsílẹ̀ ju èyí tó wà lábẹ́ HIPAA. Òfin Ìjọba Ìpìnlẹ̀ náà tún máa ń le koko tí àwọn àgbàsìlẹ̀ náà bá wà ní ìdáàbobò kúrò níbi ìṣàfihàn nípasẹ̀ ti òfin ìjọba ìpínlẹ̀ ju èyí tó wà lábẹ HIPAA lọ. Ní àwọn àsìkò tí Ẹ̀ka Ìjọba tí ó ń

mójútó ètò Ìlera bá pèsè ìtọ́jú fún aláìsàn kan tí ó ń gbé ní ìpínlẹ̀ ìtòsí, a ó tẹ̀lé òfin íjọba ìpínlẹ̀ tí ó ṣé e lò tí ó sì le koko jùlọ.

F. **<u>Pàṣípààrọ̀ Ìsọfúnni Ìlera:</u>** Ẹ̀ka Ìjọba wa ṣalábápín àwọn àgbàsílẹ̀ ìlera rẹ lọ́nà ti ẹ̀rọ alágbèéká yàbí ọ̀nà mìíràn pẹ̀lú Àwọn Páṣípààrọ̀ Ìsọfúnni Ìlera (Health Information Exchanges, “HIE”) èyí tó ṣe páṣípààrọ̀ àwọn àgbàsílẹ̀ ìlera pẹ̀lú àwọn HIEs mìíràn. Ẹ̀ka Ìjọba wa Iṣẹ́ Òjíṣẹ́ Wa tún máa ń lo àwọn ìsọfúnni àyípadà ìmọ̀ ẹ̀rọ (bíi àwọn iṣẹ́ ìfiwéránṣẹ́ tààrà, olùpèsè iṣẹ́ ìsọfúnni nípa ìlera (health information services provider, “HISP”), àti àwọn ìkànnì àwọn oníṣègùn) pẹ̀lú àkọsílẹ̀ ìlera orí ẹ̀rọ (Electronic Health Record, “EHR”) láti pín àkọsílẹ̀ ìlera rẹ fún àwọn ète tí a fàyè gbà, títí kan bíbójútó àti ìtọ́jú rẹ yóò ṣe máa bá a lọ. Àwọn HIE àti ìmọ̀-ẹ̀rọ ìpaṣípààrọ̀ dátà yóò mú kí ṣíṣe alábààpín àwọn àgbàsílẹ̀ ìlera rẹ ṣe àmúdára àwọn ìpèsè ìtọ́jú ìlera rẹ tí à ń ṣe fún ọ (fún àpẹẹrẹ, ìyẹra fún àyẹ̀wò ọ̀nà méjì tí kò yẹ). Àwọn àgbàsílẹ̀ ìlera tí a ṣe alábààpín yóò láfikún, tí ó bá ṣe é lò, àwọn àyẹ̀wò tó ṣe kókó bí àárùn kògbóògun fáírọ́ọ̀sì HIV/AIDS, àwọn àárùn ìbálòpọ̀, ìsọfúnni ti àbùdá, ìlera ọpọlọ, àti mímu ọtí àti lílo òògù olóró lọ́nà àìtọ́, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Àwọn HIE àti àwọn olùpèsè ìmọ̀ ẹ̀rọ ìpàṣípààrọ dátà máa ń kópa gẹ́gẹ́ bí alábààṣe ìṣowò wa, àtipé, nípasẹ̀ bíbáṣe lórúkọ wa, wọ́n máa ṣe ìfíṣọwọ́, ìmójùtó àti ìfipamọ́ PHI rẹ fún àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú, ìsanwó àti ìmójútó ìlera àti àwọn ìdí mìíràn tí a fọwọ́ sí. Àwọn HIE àti àwọn ìmọ̀ ẹ̀rọ ìpàṣípààrọ̀ dátà nílò láti ṣàmúṣẹ àwọn ìdáàbòbò ti ìṣàkóso, ti ara, àti ti ìmọ̀ ẹ̀rọ tí yóò dáàbòbò wíwà ní ìpamọ́ àti ìfọkàntán ìsọfúnní ìlera rẹ bóti tọ́ àti bóti yẹ. Ófin tí ó ṣe é lò lè pèsè ẹ̀tọ́ láti fòfindè, wọlé tàbí jáde kúrò ní (àwọn) HIE. Fún àlàyé sí i jọ̀wọ́ kàn sí òṣìṣẹ́ tí ó ń mójútó ohun ìkọ̀kọ̀ ní Ẹ̀ka Ìjọba ti Ìlera wa ní 833-718-1043, tàbí o lè fí ímeèlì ránṣẹ́ sí wa ní privacyofficer@trinity-health.org.

## II. Lílò tàbí ìṣàfihàn tí a fọwọ́sí pẹ̀lú ànfààní fún ọ láti gbà tàbí kọ̀

A. **<u>Ẹbí/Àwọn Ọ̀rẹ́:</u>** Ẹ̀ka Ìjọba wa yóò ṣàfihàn PHI nípa rẹ sí ọ̀rẹ́ tàbí ẹbí kan tí o ní ṣe tàbí tí ó ń san owó ìtọ́jú ìṣègùn rẹ. O ní ẹ̀tọ́ láti béèrè pé kí wọ́n mà ṣalábààpín PHI rẹ pẹ̀lú díẹ̀ tàbí gbogbo ẹbí àti àwọn ọ̀rẹ́ rẹ. Láfikún, Ẹ̀ka Ìjọba fún Ètò Ìlera wa yóò ṣàfihàn PHI nípa rẹ sí iléeṣẹ́ kan tí ó ń ṣe ìrànlọ́wọ́ nípa àwọn akitiyan ìdẹ̀kùn kúrò níbi àjálù kí ẹbí rẹ lè ba ní ìtóniléti nípa ipò rẹ, déédé bí o ti wà, àti agbègbè tì o wà.

B. **<u>Ẹ̀ka Ìjọba fún Ètò Ìlera –Atọ́nà:</u>** Ẹ̀ka Ìjọba wa lè ṣàfikún ìsọfúnni kan pàtó nípa rẹ sínú atọ́nà kan nígbà tí o bá jẹ́ aláìsàn ní ilé ìwòsàn. Ìsọfúnni yìí yóò láfikún orúkọ rẹ, agbègbè rẹ ní Ẹ̀ka Ìjọba wa, ipò tí o wà lápapọ̀ (fún àpẹẹrẹ, ó dára díẹ̀, ó wà nípò, ó burú jáì, àti bẹ́ẹ̀bẹ́ẹ̀ lọ.) àti ìbátan ti ẹ̀sìn rẹ. Ìsọfúnni atọ́nà náà, àyàfi ìbátan ti ẹ̀sìn rẹ, yóò wà ní ìṣàfihàn sí àwọn ènìyàn tí wọ́n bá béèrè rẹ látara orúkọ rẹ. O ní ẹ̀tọ́ láti béèrè pé kí orúkọ má wà ní àfikún sí atọ́nà ti Ẹ̀ka Ìjọba fún Ètò Ìlera wa. Tí o ba béèrè láti jáde kúrò ní atọ́nà náà, a kò lè fi wíwà rẹ, agbègbè rẹ, tàbí ipò rẹ lápapọ̀ tó àwọn àlejò létí.

C. **<u>Ìtọ́jú ti Ẹ̀mí:</u>** A ó fún àlùfáà ìjọ kan ní Ìsọfúnni ti atọ́nà, láfikún sí ìbátan ti ẹ̀sìn rẹ, kódà tí wọn kò bá béèrè fún orúkọ rẹ. Àwọn olùpèsè ìtọ́jú ti ẹ̀mí jẹ́ ọmọ ẹgbẹ́ ikọ̀ ìmòjútó ìlera àtipé a lè gbà àmọ̀ràn láti ọ̀dọ̀ wọn nípa ìtọ́jú rẹ. O ní ẹ̀tọ́ láti béèrè pé kí a má ṣe fún àlùfáà kankan ní orúkọ rẹ.

D. **<u>Àwọn Ìròyìn Mídíà:</u>** Ẹ̀ka Ìjọba wa yóò ṣàgbéjáde ìsọfúnni atọ́nà ti ilé ìtọ́jú sí mídíà (ní àyọkúrò ìbátan ti ẹ̀sin) tí mídíà bá béèrè fún ìsọfúnni nípa rẹ látara lílò orúkọ. Mọ̀ wipé o lè kọ̀ láti wà ní àfikún sìnú àtọ́nà náà.

## III. Lílò tàbí Ìṣàfihàn tí ó nílò Ìgbàṣẹ

A. **<u>Ìpolówó Ọjà:</u>** Dá lórí àwọn àyàfi kan pàtó tí a ṣe níwọ̀n, a nílò ìgbàṣẹ rẹ tí ò wà ní àkọ́ọ́lẹ̀ ní àwọn àsìkò tí Ẹ̀ka Ìjọba wa bá gbà èyíyòówù owó lọ́nà tààrà tàbí lọ́nà tí kìí ṣe tààrà ní pàṣípààrọ̀ fún bíbá ọ sọ̀rọ̀ náà èyí tí yóò ṣe kóríyá fún ọ láti ra ọjà tàbí ìpèsè kan tàbí fún iṣàfihàn sí ikọ̀ kẹta kan tí ó bá fẹ́ polówó àwọn ọjà àti àwọn ìpèsè wọn fún ọ.

B. **<u>Ìwádìí:</u>** Ẹ̀ka Ìjọba wa yóò gbà àwọn ìgbàṣẹ tí ó wà ní àkọ́ọ́lẹ̀ láti lò tàbí ṣàfihàn PHI rẹ fún àwọn ìdí ìwádìí tí HIPAA tàbí àwọn òfin àti ìlànà ìwádìí ti ilé ìtọ́jú bá nílò rẹ.

C. **<u>Àwọn Àkọsílẹ̀ Ìtọ́jú Àìlera ti Ẹ̀mí:</u>** Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn lílò àti ìṣàfihàn ti àwọn àkọsílẹ̀ ìtọ́jú àìlera ti ẹ̀mí nílò ìgbàṣẹ rẹ tí ò wà ní àkọ́ọ́lẹ̀.

D. **<u>Títà PHI:</u>** Dá lórí àwọn àyàfi pàtó tí a ṣe níwọ̀n, àwọn ìṣàfihàn tó bá jásí títà PHI nílò ìgbàṣẹ tí ò wà ní àkọ́ọ́lẹ̀ rẹ.

E. **<u>Àwọn Lílò àti àwọn Ìṣàfihàn:</u>** Èyíkéyìí àwọn lílò tàbí àwọn ìṣàfihàn ti PHI tí a kò júwèé sínú Àkíyèsí Àwọn Ìṣe Ìkọ̀kọ̀ lè nílò ìgbàṣẹ rẹ tó wà ní àkọ́ọ́lẹ̀ (láìjẹ́ bẹ́ẹ̀ kí HIPAA fọwọ́ sí i). ). Àwọn ìgbàṣẹ tówà ní àkọ́ọ́lẹ̀ yòó jẹ́ kí o mọ kílódé tí a fi ń lò PHI rẹ. O lẹ́tọ̀ọ́ láti dá ìgbàṣẹ padà nígbàkugbà.

## IV. Lílò tàbí Ìṣàfihàn tí Ìlànà Àrá Ìlú tàbí Òfin fọwọ́sí tàbí nílò lái sí Ìgbàṣẹ rẹ

A. **<u>Àwọn Ìdí Ìgbófinró:</u>** Ẹ̀kà Ìjọba wa lè ṣàfihàn PHI rẹ fún àwọn ìdí ìgbófinró gẹ́gẹ́ bí òfin ti fọwọ́ sí, gẹ́gẹ́ bí dídáọ̀daràn afurasí tàbí ẹni tí à ń wá mọ̀ tàbí pípèsè ìsọfúnni nípa olùfaragbà ọ̀ràn kan tàbí ẹjọ́ ọ̀ràn kan tí ó ń pa ọ́ lára.

B. **<u>Tí òfin nílò:</u>** Ẹ̀ka Ìjọba wa fún Ètò Ìlera yóò ṣàfihàn PHI nípa rẹ nígbà tí ìjọba àpapọ̀, ìjọba ìpínlẹ̀, tàbí, ìjọba ìbílẹ̀ bá nílò rẹ. Àwọn àpẹẹrẹ láfikún àwọn ìṣàfihàn láti fèsì sí àṣẹ ilé ẹjọ́/tàbí ìpẹ̀jọ́, ìfisùn ìjọba tí o pọn dandan (fún àpẹẹrẹ, àwọn ọgbẹ́ ìbọn, àwọn olùfaragbà ìwà ìkà sí ọmọdé tàbí pípa wọ́n tì), àwọn ìtọpinpin ti ìjọba, tàbí ìsọfúnni tó yẹ láti fi tẹ̀lé àwọn òfin mìíràn gẹ́gẹ́ bí gbà mábínú àwọn òṣìṣẹ́ tàbí àwọn òfin tó jọ bẹ́ẹ̀. Ẹ̀ka ti Ìjọba wa yóò ṣe ìfisùn kíkó òògùn bí kò ti yẹ àti ìsọfúnni tó jẹ mọ́ àwọn ìṣe kíkọ òògùn fúnni lọ́nà jìbìtì sí àwọn iléeeṣẹ́ ìgbófinró.

C. **<u>Ìmójútó Tàbí Ìdáàbòbò Ìlera Ìlú:</u>** Ẹ̀ka Ìjọba wa yóò lò àti ṣàfihàn PHI láti dènà de ewu tó lágbára sí ìlera àti ìdáàbòbò ti ènìyàn tàbí ti ìlú. Àwọn àpẹẹrẹ láfikún àwọn ìṣàfihàn ti PHI sí àwọn ọ̀tẹlẹ̀múyẹ́ ti ìjọba nípa bí ìtọ́jú ṣe dára tó tàbí sí àwọn iléeṣẹ́ ìlera ti ilú nípa àwọn àjẹsára, àwọn ààrùn tó ṣe é kó, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ẹ̀ka ti Ìjọba wa yóò lò àti ṣàfihàn PHI fún Ìgbòkègbodò tó jẹ mọ́ dídára, ìdáàbòbò tàbí ìlapa àwọn ọjà tàbí àwọn ìgbòkègbodò tí a ti ṣe ní déédé nípasẹ̀ FDA, láfikún sí gbígbà àti ìfisùn àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ ìkọlù, ìtọpa, àti imúṣiṣẹ́ nípa àwọn dídá ọjà padà, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

D. **<u>Àwọn Olùṣàyẹ̀wò òkú, Àwọn Olùṣàyẹ̀wò ti Ìṣègùn, Àwọn Olùdarí Ìsìnkú:</u>** Ẹ̀ka Ìjọba wa yóò ṣàfihàn PHI sí olùṣàyẹ̀wò òkú tàbí olùṣàyẹ̀wò ti ìṣègùn kan. Fún apẹẹrẹ, èyí yóò yẹ láti dá olóògbé kan mọ̀ tàbí láti mọ̀ okùnfa ikú rẹ̀. Ẹ̀ka Ìjọba wa lè tún ṣàfihàn ìsọfúnni ti iṣègùn re sí àwọn olùdarí ìsìnkú gẹ́gẹ́ bí ó ti yẹ láti ṣe àwọn ojúṣe rẹ.

E. **<u>Rírà Àwọn Ẹ̀yà Ara:</u>** Ẹ̀ka Ìjọba wa yóò ṣàfihàn PHI sí iléeṣẹ́ tó ń ra àwọn ẹ̀yà ara tàbí ohun fún ìfúnni ní ẹ̀yà ara, ojú, tàbí iṣan.

F. **<u>Àwọn Ìkópa Ti Ìjọba Tí A Ṣàyàn:</u>** Ẹ̀ka Ìjọba wa yóò ṣàfihàn PHI rẹ nípa àwọn ìkópa ìjọba gẹ́gẹ́bi ológun, ààbò orílẹ̀-èdè àti àwọn ìgbòkègbodò ìwádìí. Ẹ̀ka Ìjọba wa yóò lò tàbí ṣàfihàn PHI sí Ẹ̀ka tó ń mójútó ọ̀rọ̀ àwọn Ológun tó ti fẹ̀hìntì láti mọ̀ bóyá o yẹ fún àwọn àǹfààní kan pàtó.

G. **<u>Àwọn Àjẹsára:</u>** Ẹ̀ka Ìjọba wa yóò ṣàfihan ẹ̀rí àjẹsára sí ilé ẹ̀kọ́ kan tí òfin ìpínlẹ̀ tàbí òfin míràn bá nílò rẹ ṣáájú kí wọ́n tó gba akẹ́kọ̀ọ́ kan wọlé.

## V. Àwọn Ẹ̀tọ́ Ìsọfúnni Ti Ìlera Rẹ

O ni àwọn àwọn ẹ̀tọ́ àládàáni wọ̀nyìí nípa PHI rẹ:

A. **<u>Ẹ̀tọ́ Láti Ṣàyẹ̀wo Àti Láti Ṣe Ẹ̀dà:</u>** Lábẹ́ àwọn àyàfi pàtó tí a ṣe níwọ̀n, o ní ẹ̀tọ́ láti gbà PHI rẹ àti láti ṣàyẹ̀wò kí o sì ṣe ẹ̀dà PHI rẹ lo\pin ìgbà tí dátà náà bá ti wà ní sẹpẹ́.

Tí Ẹ̀ka Ìjọba wa bá kọ̀ ibéèrè rẹ láti gba PHI rẹ, a ó fi tó ọ létí nípasẹ̀ kíkọ pẹ̀lú ìdí tí wọ́n fi kọ̀ ọ́. Fún àpẹẹrẹ, o kò lẹ́tọ̀ọ́ sí àwọn àkọọ́lẹ̀ ti ìtọ́jú àìlera ọkàn tàbí lài ṣàyèwò ìsọfúnni náà léyìí tó wà labẹ́ òfin tó kọ̀ fún gbígbà rẹ. O lè ní ẹ̀tọ́ láti ṣàtúnyẹ̀wò ìpinnu yìí.

O tún ní ètọ́ béèrè fún PHI rẹ ní ìlànà ti ẹ̀rọ alágbèéká ní àwọn ìgbà tí Ẹ̀ka Ìjọba wa bá ti ń ṣàmúlò àwọn àgbàsílẹ̀ ti ìlera ní ọnà ẹ̀rọ àyélujara. O lè rí ìsọfúnni gbà látara ìkànnì ti aláìsàn tí Ẹ̀ka Ìjọba wa bá ṣàgbékalẹ̀ rẹ.

Wọ́n yóò gbà owó tí kò ga ju ara lọ lọ́wọ́ rẹ fún ṣíṣe ẹ̀dà ní ìbámu pẹ̀lú òfin ìjọba àpapọ̀ tàbí ìjọba ìpínlẹ̀ tó ṣe é lò.

Fún ìrọ̀rùn rẹ, díẹ̀ nínú àwọn PHI rẹ yóò ṣe é rí gbà ní ìkànnì aláìsàn kan. Rírí àlékún PHI gbà lè ṣe é ṣe látàra ìbéèrè láti rí i gbà.

B. **<u>Ẹ̀tọ́ láti Ṣàtúnṣe:</u>** O lẹ́tọ̀ọ́ láti ṣàtúnṣe PHI rẹ fún odiwọ̀n ìgbà tí Ẹ̀ka Ìjọba wa fún Ètò Ìlera bá ti ṣàmúduró dátà náà. O gbọ́dọ̀ jẹ́ kí ìbéèrè rẹ fún àtúnṣe PHI rẹ wà ní kíkọ sí privacyofficer@trinity-health.org tàbí, sí ọ̀ṣìṣẹ́ ètò ìlànà ìkọ̀kọ̀ wa ní 20555 Victor Parkway Livonia MI 48152 láfikún sí ìdí rẹ láti ṣàtilẹyìn fún àtúnṣe tí o béèrè fún.

Síbẹ̀síbẹ̀, Ẹ̀ka Ìjọba wa yóò kọ̀ ìbéèrè rẹ fún àtúnṣe tí:

i. Ẹ̀ka Ìjọba wa kò bá ṣẹ̀dá ìsọfúnni náà;
ii. Ìsọfúnni náà kò sí lára àkọsílẹ̀ tí a yàn;
iii. Tí ìsọfúnni náà kò ní sí nílẹ̀ fún àyẹ̀wò rẹ (látàrí ìpò tàbí àdámọ́); tàbí

iv. Ìsọfúnni náà péye ó sì pé.

Tí ìbéèrè rẹ fún àwọn àyípadà nínú PHI rẹ ti wà ní kíkọ̀, Òṣìṣẹ́ Ètò Ìkọ̀kọ̀ náà yóò fi tó ọ létí ní kíkọ́ pẹ̀lú ìdí fún kíkọ̀. Òṣìṣẹ́ Ètò Ìkọ̀kọ̀ náà yóò tún fi ẹ̀tọ́ rẹ láti kọ ọ̀rọ̀ tí o kò fi faramọ́ kíkọ̀ náà. O lè béèrè pé kí Ẹ̀ka Ìjọba fi kún ìbéèrè rẹ fún àtúnṣe àti kíkọ̀ nígbàkugbà tí Ẹ̀ka Ìjọba wa bá ti padà ṣàfihàn ìsọfúnni tí o fẹ́ kí yí padà. Ẹ̀ka Ìjọba wa lè ṣètò àtakò sí ọ̀rọ̀ àìfaramọ́ rẹ àtipé tí wọn yóò sì pèsè ẹ̀dà àtakò náà fún ọ.

**C.** **<u>Ètó sí Àkọsílẹ̀:</u>** O lẹ́tọ̀ọ́ láti gbà àkọsílẹ̀ àwọn ìṣàfihàn PHI rẹ tí Ẹ̀ka Ìjọba ti ṣe, àyàfi àwọn ìṣàfihàn wọnyìí:

i. Láti ṣe àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú, ìsanwó, tàbí ìmójútó ìlera;
ii. Sí ẹ;
iii. Sí àwọn ènìyàn tí wọ́n wà ní àmójútó rẹ;
iv. Fún ààbò orílẹ̀-èdè tàbí àwọn ìdí ti ìwádìí; tàbí
v. Sí àwọn ọ̀gbà ẹ̀wọ̀n tàbí àwọn òṣìṣẹ́ agbófinró.

O gbọ́dọ̀ ṣètò ìbéèrè fún àkọsílẹ̀ àwọn ìṣàfihàn PHI rẹ ní kíkọ sí Ẹ̀ka Ìjọba wa ní kíkọ sí Ẹ̀ka Ìjọba wa ní privacyofficer@trinity-health.org or, sí òṣìṣẹ́ ètò ìlànà ìkọ̀kọ̀ wa ní 20555 Victor Parkway Livonia MI 48152.

O gbọ́dọ̀ ṣàfikún àkókò àkọsílẹ̀ náà, léyìí tí kò ní gùn ju ọdún 6 lọ. Lẹ́ẹ̀kan ní àárin oṣù 12, Ẹ̀ka ìjọba wa yóò pèsè àkọsílẹ̀ àwọn ìṣàfihàn PHI rẹ láì gbowó. Ìbéèrè àfikún èyíkéyìí fún àkọsílẹ̀ láàrin àkókò náà yóò wà gbà kí o sanwó tí ko ga ju ara lọ fún ìsètò àkọsílẹ̀.

**D.** **<u>Ẹ̀tọ́ láti Béèrè fún Ìfòfindè:</u>** O lẹ́tọ̀ọ́ láti béèrè fún àwọn ìfòfindè lórí àwọn pàtó lílò àti ìṣàfihàn PHI rẹ kan láti ṣe àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú, ìsanwó tàbí ìmójútó ti ìlera tàbí láti ṣe irúfẹ́ ìṣàfihàn náà. Síbẹ̀síbẹ̀, Ẹ̀ka Ìjọba wa.

**E.** **<u>Ẹ̀tọ́ láti béèrè fún ìfòfindè sí Ètò Ìlera kan:</u>** O lẹ́tọ̀ọ́ láti béèrè fún ìfòfindè lórí ìṣàfihàn PHI rẹ sí ètò ìlera (fún àwọn ìdí ti àwọn iṣẹ́ ìsanwó tàbí ìmójútó ìlera) ní àwọn ìgbà tí o sanwó fúnra rẹ, ní pípé, fún àwọn ohun tí o gbà tàbí àwọn ìpèsè tí o ṣe. A ó gba irúfẹ́ àwọn ìbéèrè nàá wọlé.

**F.** **<u>Ẹ̀tọ́ sí Àwọn Ìbáraẹnisọ̀rọ̀ tó Pamọ́:</u>** O lẹ́tọ̀ọ́ láti gba àwọn ìbáraẹnisọ̀rọ̀ PHI rẹ tó pamọ́ nípasẹ̀ àwọn ọ̀nà mìíràn tàbí àwọn agbègbè mìíràn. Fún àpẹẹrẹ, o lè béérè pé kí Ẹ̀ka Ìjọba wa kàn sí ẹ ní ibi iṣẹ́ tàbí nípasẹ̀ íméèlì nìkan. Tí o bá ti pèsè ímeèlì rẹ, Ẹ̀ka Ìjọba wa lè kàn sí wa látara ímeèlì yẹn àyàfi tí o bá béèrè fún ọ̀nà ìbásọ̀rọ̀ mìíràn

**G.** **<u>Ẹ̀tọ́ Láti Gbà Ẹ̀dà Àkíyèsí:</u>** O lẹ́tọ̀ọ́ láti gbà ẹ̀dà ìwé ti Àkíyèsí Àwọn Ìṣe ètò Ìkọ̀kọ̀, tí o bá béèrè fún un.

## VI. Ìjàmbá PHI tí kòní ààbò

Tí ìjàmbá PHI tí ó ń dà ọ́ láàmú bá ṣẹlẹ̀, Ẹ̀ka Ìjọba nílò láti fi tó ọ létí ìjàmbá náà. Alábàáṣe òwò wa lè pèsè Irúfẹ́ àkíyèsí náà lórúkọ wa.

**VII. Pínín àti Lílò Ìsọfúnni Ìlera rẹ Papọ̀**

Awọn ọmọ ẹgbẹ́ Trinity Health, Ẹ̀ka Ìjọba wa àti àwọn òṣìṣẹ́ ìṣègùn máa ń lò PHI rẹ fún àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú, ìsanwó àti/tàbí fún ìmójútó ìlera tí HIPAA fọwọ́sí nípa ti àwọn aláìsàn wa tí a jọ ní àfẹnukò pẹ̀lú. Nígbà ìpèsè ìtọ́jú fún ọ àti nípasẹ̀ èróńgbà Ẹ̀ka Ìjọba wa láti ṣe àmúdára ìlera àwùjọ, a ó pín PHI rẹ pẹ̀lú àwọn iléeṣẹ́ àti àwọn olùpèsè mìíràn tí wọ́n ti gbà láti tẹ̀lé àwọn ìlànà tí a kà sí ìsàlẹ̀ wọ̀nyìí:

A. **<u>Oṣìṣẹ́ Ìṣègùn.</u>** Òṣìṣẹ́ ìṣègùn àti Ẹ̀ka Ìjọba wa máa ń kópa papọ̀ ní ipò ìtọ́jú ìlera tí a ti ṣètò láti pèsè ìtọ́jú ìlera fún ọ ní Ẹ̀ka Ìjọba wa. Ẹ̀ka Ìjọba wa àti àwọn òṣìṣẹ́ ìṣègùn rẹ tí fẹnukò láti tẹ̀lé àwọn ìlàna Àkíyèsí yìí nípasẹ̀ PHI tí a ṣẹ̀dá tàbí gbà gẹ́gẹ́ bí ara ìpèsè ìtọ́jú ìlera fún ọ ní Ẹ̀ka Ìlera wa. Ẹ̀ka Ìlera wa àti àwọn òṣìṣẹ́ wa yóò gbà àti lò PHI láti mú àwọn èròńgbà ti ìtanilọ́rẹ wa, láfikún ìgbéléwọ̀n àti ìmúdára bí ìtọ́jú ṣe dára tó.

B. **<u>Jíjẹ́ ọmọ ẹgbẹ́ ní Trinity Health.</u>** Ẹ̀ka Ministry Ìjọba wa àti àwọn ọmọ ẹgbẹ́ Trinity Health mìíràn máa ń kópa papọ̀ ní ipò ìtọ́jú ìlera tí a ti ṣètò fùn àtúnyẹ̀wò ìmúlò, ìgbéléwọ̀n dídára, àti àwọn ìgbòkègbodò tí ó jọ bẹ́ẹ̀. Gẹ́gẹ́ bí ara Trinity health, ètò ìtọ́jú ìlera ti ìjọ Kátólíìkì jákèjádò orílẹ̀ èdè, Ẹ̀ka Ìjọba wa àti àwọn olùpèsè ìtọ́jú ìlera ní Trinity Health máa ń pín PHI fún àtúnyẹ̀wò àmúlò, ìgbéléwọ̀n dídára, àti àwọn ìgbòkègbodò ti Trinity Health tó jọra wọn, olú iléeṣẹ́, àti àwọn ọmọ ẹgbẹ́ rẹ̀. Gbogbo ọmọ ẹgbẹ́ Trinity Health ti fẹnukò láti tẹ̀lé àwọn ìlàna Àkíyèsí yìí nípa PHI tí a ṣẹ̀dá tàbí gbà gẹ́gẹ́ bí ara àwọn ìgbòkegbodò àtúnyẹ̀wò àmúlò àti ìgbéléwọ̀n dídára.

Jọ̀wọ́ lọ sí àwọn ẹ̀rọ ayélujára Trinity Health fún àtòkọ àwọn iléeṣẹ́ tó jẹ́ ẹgbẹ́ ní http://www.trinity-health.org/. Tàbí, lọ́nà mìíràn, o lè pè Òṣìṣẹ́ Ètò Ìkọ̀kọ̀ láti béèrè fún ohun kan náà ní 833-718-1043, or you can email us at privacyofficer@trinity-health.org.

C. **<u>Àwọn Alábàáṣe òwò</u>** Ẹ̀ka Ìjọba wa yóò pín PHI rẹ pẹ̀lú àwọn alábàáṣe òwò àti àwọn alágbàṣe kékeré tí a gbà láti kópa nínú àwọn òwò lórúkọ wa, láfikún Trinity Health tí ó ń ṣe àwọn iṣẹ́ òwò fún Ẹ̀ka Ìjọba.

D. **<u>Àwọn Olùpèsè Ìtọ́jú Ìlera àti Àwọn Adarí Ìtọ́jú</u>** O gbà ìtọ́jú láti Ẹ̀ka wa tí a pèsè ní ìṣètò ìtọ́jú tí ó so pọ̀, níbí tí ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn olùpèsè lóríṣiríṣi àti ní ọ̀pọ̀ àwọn ìṣètò ìtọ́jú rí àwọn aláìsàn gẹ́gẹ́ bí ìtẹ̀síwájú ìtọ́jú àti ìpèsè ìtọ́jú tó péye. Ẹ̀ka Ìjọba wa máa ń pín PHI pẹ̀lú àwọn olùpèsè ìtọ́jú mìíràn àti àwọn olùdarí ìtọ́jú tí wọ́n ṣíṣẹ́ papọ̀ láti pèsè ìtọ́jú, gba owó, ṣe àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú ìlera. a máa ń pín PHI rẹ nípasẹ̀ ti ayélujára ní àwọn ọ̀nà tó pọ̀ pẹ̀lú àwọn olùpèsè tí ó niṣe pẹ̀lú ìpèsè ìtọ́jú àti ìdarí ìtọ́jú. A lè pín PHI rẹ látara ìsopọ̀ tàárà sí àkọsílẹ̀ ìlera ti àyélujára ti àwọn olùpèsè mìíràn. A lè pín PHI rẹ ní ìpàṣípàárọ̀ ìsọfúnni ìlera tàbí ti ìmọ̀ ẹ̀rọ tí yòó mú kí àwọn olùpèsè lábẹ́lẹ̀ àti àwọn olùdarí ìtọ́jú gbà ìsọfúnni rẹ. A lè pín PHI rẹ nípasẹ̀ gbígbé lọ sí àwọn àpótí àtẹ̀jíṣẹ́ àwọn olùpèsè lọ́nà tí kò léwu.

**VIII. Àwọn Àyípadà sí Àkíyèsí yìí.** Ẹ̀ka wa yóò tẹ̀lé àwọn ìlànà ti Àkíyèsí tó ń ṣiṣẹ́ lọ́wọ́. A ṣe àdáni ẹ̀tọ́ láti ṣe àwọn àyípadà tó ṣe kókó sí àwọn ìlànà Àkíyèsí rẹ àti láti jẹ́ kí àwọn ìpèsè Àkíyèsí tuntun náà ṣiṣẹ́ fún gbogbo PHI tí ó bá ń mójútó. Ẹ̀ka Ìjọba wa fún ètò Ìlera yóò pín / pèsè Àkíyèsí tí a tún yẹ̀wò fún ọ ní ìbẹ̀wò àkọ́kọ́ rẹ lẹ́hìn àtúnyẹ̀wò Àkíyèsí náà ní àwọn ìgbà tí ó bá ti ṣe àyípadà tí ó ṣe kókó nínú Àkíyèsí náà. O lè tún béèrè fún ẹ̀dà

Àkíyèsí tí ó wà lọ́wọ́ lọ́wọ́ nígbàkugbà. Àwọn ẹ̀dà tí ó wà lọ́wọ́lọ́wọ́ ti wà ní gbígbé sórí ojú ewé ayélujára ti Ẹ̀ka Ìjọba.

Àwọn Ẹ̀dùn Ọkàn. Tí o bá nígbàgbọ́ pé wọ́ ti tẹ àwọn ẹ̀tọ́ sí ètò ìkọ̀kọ̀ rẹ, o lè fi ẹjọ́ sùn Ọ̀ṣìṣẹ́ Ètò Ìkọ̀kọ̀ rẹ tàbí sí Akọ̀wé Ẹ̀ka ti Ìlera àti Ìpèsè ti Ènìyàn. A gbọdọ̀ jọ̀wọ́ gbogbo àwọn ẹ̀dùn ọkàn tí a kọ tààrà sí privacyofficer@trinity-health.org tàbí sí ọ̀ṣìṣẹ́ ètò ìlàna ìkọ̀kọ̀ ní 20555 Victor Parkway Livonia MI 48152.

## IX. *A kò ní dá ọ lóró fún ìfisùn èyíkéyìí.*

**Ọ̀ṣìṣẹ́ Ètò Ìkọ̀kọ̀ - Àwọn Ìbéèrè / Àwọn Ẹ̀hónú / Àlékún Ìsọfúnni Tí o bá ní èyíkéyìí ìbéèrè, ẹ̀hónú, tàbí fẹ́ àfikún ìsọfúnni nípa àwọn ọ̀rọ̀ tí Àkíyèsí Ìṣe Ìkọ̀kọ̀ yìí kó sínú tàbí fẹ́ àlékún ìsọfúnni nípa àwọn ìlànà àti àwọn ìgbésẹ̀ ìkọ̀kọ̀ ti Ẹ̀ka Ìjọba fún Ètò Ìlera, jọ̀wọ́ kàn sí ọ̀ṣìṣẹ́ ètò ìkọ̀kọ̀ ní 833-718-1043, tàbí o lè fi íméèlì ránṣẹ́ sí wa ní privacyofficer@trinity-health.org.**